# ELETI-ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. NO 817 LAGOS SATURDAY APRIL 28,- MAY 5. 1962. KOBỌ MEJI (2D)


# Oyinbo Ologun Ti Ijoba Nigeria Ni Ki O Kuro Nilu F'ake Kori

Eko— Ni ijẹta ni awọn Alaṣẹ Ijọba Apapọ Nigeria fun Oyinbo ologun kan ti orukọ rẹ nje Frank Leslie Tate, ni iwe pe awọn fun ni wakati mejidinladọta ki o fi palẹ gbogbo ẹru rẹ mọ, ki o si kuro ni ilu yi patapata.

Onirohin "Eleti-ọfẹ" sọ wipe nigbati on fi oju kan Oyinbo na, o ni aṣẹ-onikurnọ yi ko le lọ rara nitoripe on ko mọ ẹṣẹ ti on ṣẹ Ijọba na. O tun tẹ siwaju wipe aya on, ọmọ Nigeria ti on ṣẹṣẹ gbe ni iyawo ti fẹrẹ bi ọmọ nisisiyi, ṣe nwọn fẹ ki on fi silẹ ki o ma jiya ni.?

Oyinbo na ni ọnini ko si lọwọ on tabi awọn Alaṣẹ Ijọba na fẹ ki on f'ẹsẹ rin lọ si ilu on na ni? O ni ọrọ wọn na ko ye on rara.

Ju gbogbo rẹ lọ, o ni on ti fi ọrọ na le lọya on lọwọ ki o ma ba iṣẹ lọ.

## Gudugbe Ja! Ofo Se Oba Ethiopia

ADDIS ABABA – Ọmọ'ba'kunrin ti orukọ rẹ nje Sahle Selassie, ti o jẹ ọmọkunrin kekẹkere fun Alaiyeluwa Haile Selassie, Ọba ilu Ethiopia, ni a gbọ wipe o jade laiye ni ọjọ Monday, ọsẹ yi, lẹhin aisan ọjọ gbọọrọ.

A fi wosika wa yi ba Alaiyeluwa, Haile Selassie. Kini kẹdun ọfọ iku ọmọ rẹ, ki Oluwa Olodumare Ọba Olutunu tuu ninu. Eyi ni ajalu nla keji ti ọba na ri l'ẹdunni, ti iku Ẹni-Ọla iyawo rẹ ni akoko ki ti ọmọ rẹ to tẹlẹ.

Ki Odumare da irufẹ eyi duro. Amin.

## Alaye Oro Egbe Omo Ilorin

E jọwọ e gba mi laye ninu iwe irohin nyin lati da Alhaji A. W. Anifowoshe lohun lori ọrọ ti o sọ sinu Eleti-Ọfẹ ti o jade ni 14/4/-62 nipa Ẹgbẹ ọmọ Ilorin ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ ni Mushin.

Emi ti mo akọwe yi jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Ilorin ti o lọ sile Alufa Ashafa ti nwọn ni awọn fi ṣe Alaga ni aipẹ yi ni Paul Okuntọla Street, Mushin. Nitotọ a ko ri ki nwọn se ipade kan nibẹ. Nitorina ẹniti o ba sọ wipe ẹṣẹ ẹgbẹ na koi ti mulẹ ko jẹbi rara.

A gba iwe ontẹ oba fun ẹgbẹ ko wipe ki ẹgbẹ fi'di mulẹ a ti pe ko wipe ki awọn miran ma da ti wọn silẹ.


(Wo yoku loju ewe kẹjọ)



**WANTED**

Bank Notes Of French African Territories

Offers:

B M / BLPR
BCM/MONO
LONDON W. C. 1.



**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY WARRI SAPELE,
ABA, KANO, ZARIA, JOS,
LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell
Telephone London Wall 4303 — Cable & Telegrams Natbaniger : London
Head Office Representatives in London.
E. Akinwunmi Doherty,
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURGH


## IKEDE

Awọn Ẹgbẹ Eko PARAPỌ (Lagos Citizens Rights Protection Council) yio se ipade gbogbo ọmọ Ẹgbẹ yi ni Ọgba CORONA Cinema ni Ita Faji L'eko ni agogo mẹrin-abọ (4.30 p.m) ni ọjọ Atalata (Tuesday) ọjọ kini oṣu May 1962.

## Baba Kan Pe Dokita L'ejo Nitoripe Omo Re Ku

Onitsha—Laipẹ yi ni ọkunrin onisowo ara Abakaliki kan ti orukọ rẹ njẹ Kalu Okoro Ajegbo, pe dokita E. S. Etuk lejọ si kotu nla, o ni on fẹ gba adọtaleloogbẹdọgbọn pọnun (£5,050) lọwọ rẹ fun iṣẹ lila-labẹ ti o ṣe fun ọmọ on, ti ọmọ na si di oku ọrun.

Ẹsun ti baba ọmọ na fi sinu iwe ipẹjọ rẹ ni wipe ninu oṣu August ọdun ti o kọja, dokita Etuk fi ọbẹ ṣe iṣẹ, o si la ọmọ on lọbẹ fun aisan ti o nṣe ọmọ on na, ti orukọ rẹ njẹ Kalu Okoro, ẹni ọgbọn ọdun, lẹhin ọjọ karun ti o ti ṣe iṣẹ na fun un ni o ku.

Iṣẹ akọwe-kotu ni ọmọ ti o ku na nṣe ninu Kotu-nla ni ilu Onisha ki o to ku.

Iwe-ipẹjọ na ti tẹ dokita na lọwọ, ṣugbọn adajọ Kotu na koi ti sọ ọjọ ti on yio gbọ ọrọ ẹnu baba ọmọ na.

## Awon Olopa ko Awon Alawo-Opa Ilu Ibo

Owerri—Laipẹ yi ni ọga ọlọpa ko ọdunrun awọn ọlọpa lọ sinu igbo awọn alawo-ọpa kan, ti wọn npe orukọ wọn ni "Igwe Kala" Juju ni ilu Ibo, eyiti Ijọba ti fi igba kan wipe on kogbọdọ gbọ wipe ẹnikan tun nṣe mọ, lati lọ ko awọn olori awo-ọpa na. Nigbati nwọn de ibẹ ọwọ awọn ọlọpa na tẹ enia metadinladọta ati olori-awo wọn.

Onirohin wa fi ye wa pe, nigbati awọn ọlọpa yi wọ igbo-malẹ awọn alawo-ọpa na, ọwọ wọn tẹ ọpọlọpọ iwe (lẹta) ti awọn ti o wa nibi iṣẹ pataki-pataki kọ si awọn alawo-ọpa na pe ki nwọn ba awọn ṣe etutu ki awọn le ni ilọsiwaju nibi iṣẹ ọba ti awọn wa ẹlomiran ni ki nwọn ba on doju ọta on bo'le. Oriṣiṣi nkan bi ere ṣigidi, ikọpa, ori-ẹran ti nwọn fi rubọ, igbadi, ikọrun, aba ati awọn nkan bẹbẹ ni awọn ọlọpa ko jade.

Awọn ọlọpa gbidanwo lati da'na sun igbomọlẹ awọn alawo-ọpa na, nwọn da epo kẹrosini ati bẹtiro sii, nwọn kan ina sii, ṣugbọn igbo na kọ ko gbina. Sibẹsibẹ awọn ọlọpa na ko fi inu igbo na silẹ; nwọn nṣọ ibẹ lọsan ati loru, nigbati o di ọjọ kẹta ti nwọn ti wa nibẹ ni nwọn to le da'na sun igbo-malẹ na, ti nwọn si sun patapata.

## Ka Irohin Ayiluka Lose Ti Mbo

## AWO'RAWO

Eyi ni awọn nkan ti yio ṣẹlẹ si ọ ni ọsẹ yi.

AQUARIUS (Jan 20–Feb 18) Ṣọra lati lo agbara ti o ba ni lọsẹ yi fun ohun rere.

PISCES (Feb 19–Mar 20) Ma ṣe tan ara rẹ jẹ; awọn iṣẹ ọna ti o ba dawọle yio bọ si rere.

ARIES (Mar 21–April 19) Ki o ṣe suru ki ọpọlọpọ nkan kekeke ma ba mu ọ binu.

TAURUS (April 20–May 20) Awọn isoro dle ti o wa fun ọ yio ka kuro, ṣugbọn ki o ma ko wahala s'ọkan ara rẹ.

GEMINI (May 21–June 20) Sinmi fun wahala atẹhin wa, ki o ma si jowu.

CANCER (June 21–July 20) Ṣọra nipa ode lilọ, ki o si fi ọgbọn yanju isoro ti o wa ni iwaju rẹ.

LEO (July 21–Aug 22) Bi o ba nwa moto, ki o ṣọra loju ọna. Ju gbogbo rẹ lọ, ọsẹ yi dara fun ọ.

VIRGO (Aug 23–Sep 23) Rin mọ ẹbi tabi ọrẹ ki arẹ-ọkan rẹ le ka kuro.

LIBRA (Sep 23–Oct22) Orire wa fun awọn nkan ti o ba dawọle, ṣugbọn o nkọ ominu lati dawọle nwọn.

SCORPIO (Oct 23–Nov 21) Maṣe ba ẹnikẹni ja, ki o ba le ri nkan rere gba lọse yi.

SAGITTARIUS (Nov 22–Dec21 Awọn isoro kan wa ti o ni lati fi ọgbọn yanju nwọn. Ilera wa fun o lọsẹ yi.

CAPRICORN (Dec 22–Jan19) Lo agbara ati okun-inu re si ọna rere ninu ọsẹ yi. Ko si Ifoya rara.

## Enia Pataki Omo Nigeria To Foju Nilu Oyinbo



Ọgbẹni Joseph Ojo, M.B.E., ti o ti ṣiṣẹ olukọ ninu ilewe giga, King's College, l'Eko fun bi ọdun merin-le-lọgbọn ni a nwo ninu aworan yi ni apa osi, ti o duro ti Olotu Ijọba Gẹsi, Ọgbẹni Harold Macmillan nigbati o lọ ta asia fun ninu ile rẹ nilu nla London.

Awọn asia ti o nta na jẹ eyiti nwọn fi nkowo jọ fun iranlọwọ awọn afọju. Ọgbẹni Ojo paapa foju lẹhin ti o gb'oye iṣẹ lọya ti o lọ kọ tan.

# Onte Titun Ilu Honduras



Ontẹ Titun ti o ṣẹṣẹ jade nilu British Honduras pẹlu aworan awọn ẹiyẹ iha Gusu ati ilẹ arin ni'lẹ Amẹrika ni oriṣiriṣi awọ ni a nwo yi.

Awọn owo ontẹ na, gẹgẹbi a tile pe ni owo ti wa ti a nlo, jẹ nkan bi epini de ponun kan loriṣiriṣi.

## Awon Obinrin Oyinbo Ko Fe Mu Siga Mo

LONDON - Ki o toto ọdun kan si igbati a wa yi, siga mimu ko ni po tobẹ mọ ni ilu Oyinbo irohin yi ni a ri gba lẹna lọwọ onirohin Eleti-Ọfẹ ti o wa nilu Oyinbo Onirohin wa na ni gẹgẹbi iwe ti awọn ogunna gbomgbo ọmọ ẹgbẹ onisegun Gẹsi ṣẹṣẹ fi sita, awọn ni siga mimu lo nmu arun buruku kan ti o nda ọgbẹ'nu (Cancer) silẹ.

Nwọn ni arun buruku yi si ti mu ori buruku ba ọpọlọpọ enia laiye, gbogbo awọn onisegun agbaiye si ti nwa egbogi arun Cancer na kiri titi ṣugbọn ọwọ wọn koili tẹe. Nwọn ni o buruju arun ẹtọ lọ.

Nitori eyi, ogunlọgọ awọn obinrin ilu Gẹsi ti nwọn ti nmu siga onipepa ri ti kọ ọ silẹ nisisiyi, nwọn ni ikoko mimu (Pipe) ni awọn yio ma mu. Ọpọlọpọ awọn Oyinbo oni-siga ni nwọn si ti nyi iṣẹ siga ṣiṣe wọn pada si ewe taba alagolo nisisiyi. Awọn Oyinbo oni-ikoko-mimu paapa si ti bẹrẹsi ṣe ti awọn obinrin lọtọ

## Olotu Ile Eko Awon Aditi Nfe Iranlowo

Ibadan - Laipẹ yi ni ọga ile ẹkọ awọn aditi ni Ibadan, Ọgbẹni Andrew Foster fi iwe ikede s'ede wipe awọn nfẹ iranlọwọ owo tabi nkan bẹẹbẹ lọwọ awọn ara Nigeria jake jado fun ile ẹkọ awọn aditi-ọmọ ti awọn da silẹ lọna Ijẹbu ti awọn npe ni Ibadan Mission School for the Deaf.

(Wo yoku loju ewe karun)

## Obinrin Kan Bi Omo Oyun Odun Marun Nilu Aba

ABA - Ogunlọgọ awọn enia lo nsare lọ si abule kan ti nwọn npe ni Obiora, l'Aba laipẹ yi lati lọ wo iran obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Eunice Uran, ẹni ọdun mejidilọgbọn, ti o bi ọmọ ti o ti nru oyun rẹ kiri fun ọdun marun si inu ọgba ile ẹsin awọn oni sọsi-elekun ti nwọn npe ni "Faith Tabernacle".

Onirohin wa fi ye wa pe ni abule kan ti nwọn npe ni Akpodim Mbaise, lagbegbe Owerri ni obinrin na ti gbe oyun na wa sibi aladura pẹlu ọkọ rẹ ti o nse iṣẹ Kapinta. Obinrin na ni ko si ẹniya ti awọn aladugbo ko fi on ṣe tan lori oyun na, o ni ṣugbọn on fi ọkan on si ọdọ Jesu, on si mọ wipe o jẹ ki on bi ọmọ na lọjọ kan.

Nwọn ti se ikomọjade ọmọ na, nwọn si sọ ọ ni Ọgechuku itumọ eyi ni "Asiko Ọlọrun" ni ede yiabo, "God's Time."

## Awon Oyinbo S. I. M. Ko Ile Eko Tuntun Sil Igbaja

Igbaja—Laipẹ yi ni gbogbo awọn onigbagbọ ti o wa ni agbegbe Offa, Oro Ọlẹ ati awọn ilu miran bẹẹ ṣe pejọ si ilu Igbaja fun eto isile tuntun ti awọn Oyinbo ojiṣẹ-Ọlọrun ti orukọ ijọ wọn njẹ Sudan Interior Mission, ṣẹṣẹ kọ sibẹ.

Oyinbo alufa olori ijọ wọn, ti nwọn npe orukọ rẹ ni Rev G. Crouch, ni o si ile ẹkọ tuntun na. Ninu ọrọ alufa na, o wipe ẹgbẹdọgbọn ponun (£5,000) ni awọn fi pari ile na; atipe ninu ile na ni awọn yio ti ma kọ gbogbo awọn alufa ijọ wọn ti yio ma jihin rere kakiri gbogbo ilẹ Nigeria.

# ELETI--OFE

ANJUWON KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Koṣẹkọ Street, Lagos. "ELETI ỌFẸ," LAGOS.

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 817. SATURDAY APRIL 28 - MAY 5, 1962


# Oro Enia Kika Nile Nigeria

A ro si ẹ tọ lati maa fi wosika asaro ọrọ wa ṣe ẹnyin ọkawe wa ni iranti l'ẹkọkan titi di ọjọ na yio fi ṣe Ijọba ma ba ṣe ẹnikẹni leri ọrọ enia kika ti Ijọba wa fẹ ṣe ni ọjọ kẹdogun oṣu May, ti o mbọ yi.

A fẹ ki gbogbo enia mọ wipe ko si ọrọ owo-ori tabi owo-ode sisan ninu enia kika na rara, ki eyi maṣe jẹ ifoiya fun ẹnikẹni, nitoripe t'ọmọde-t'agba, t'ọkunrin ati obinrin ni nwọn yio ka, lati le mọ iye enia ti o wa ninu awọn ilu kọkan jake jado ilẹ Nigeria.

Anfani nla si ni enia kika na yio ṣe fun awọn enia ile nitoripe nipa mimọ bi enia ti pọ to ni ilu kọkan ni Ijọba yio fi mọ iwọn nkan anfani ti o tọ si ilu bẹ lati ṣe.

Lẹkẹnsi, a tun bẹ ẹnyin enia wa wipe ki ẹ yọnda ara nyin fun awọn oniṣẹ akọnia, ki ẹ si ṣe iranlọwọ fun wọn.


E mase fi omi sofo





# IWE SI OLOTU

## Kinni A Se o?

Ẹ jọwọ, ẹ gba wa, ẹ ba wa bi awọn Ijọba ilu Aganyin (Ghana) lere ẹṣẹ ti a ṣẹ, ti o fi di wipe nwọn ko gb awọn iyawo wa laye mọ lati wọ'lu Ghana wa ba wa.

Laipẹ yi, o to awọn ogun enia ara ilu Nigeria ti nwọn ni nwọn ko gbọdọ sọkalẹ si ebute Tarkoradi, ni gbara ti ọkọ ti nwọn wọ ti gunlẹ s'ebute.

Nwọn sọ wipe a ko jẹ ki awọn ọmọ awọn ri iṣẹ ṣẹ mọ; nwọn ni gbogbo iṣẹ kekeke ti awọn ọmọ awọn ko ba maa ṣe ni awọn ara Nigeria ti ra kaka mọ. Bẹ Ijọba Nigeria kii ni ọmọ Ghana kan lara nibikibi niun iṣẹ ni Nigeria.

Ẹ ba wa bere, kini aṣe o?

Emi ni,

Sekondi, Ghana. O. Akande

## Onigbagbo Ko S... Mo, Onigbagb... Lo'Ku

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba m... laye ki nkin nyin lẹhin fu... ọrọ wosika ti ẹ fi ki wa k... ọdun lọsẹ ti o kọja. Ki... maṣe purọ, ọrọ naṣmu aw... onigbagb lọkan pupọ.

Ti a ba ni ki a ma ṣe... iwasu etitọ ọrọ na, iwe... irohin yi a kun patapata. Nitotọ ni ọpọlọpọ awa... onigbagbọ ti di onigbagbe, ni ojojumọ ni a nkan Jesu Kristi ti o wa larin wa mọ igi agbelebu pẹlu iwa buruku wa. Iwa awọn ẹlomiran ninu wa si ju ti Judasi lọ.

Ọpọlọpọ awọn onigbagbọ lo ti lọwọ ninu a nfi ọmọ-ọlọmọ wa owo; omiran ni ti on ba ti ndawo kilasi, dandan ni ki on wọ Ijọba ọrun. Iwa ika ati kẹnimani si njọba lọkan wa.

Ẹ ṣọra, Ijọba ọrun ku si dẹdẹ!

Emi ni

Abẹokuta Baba Ijọ




# ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'EJỌ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28, Koṣẹkọ Street, Lagos. "ELETI OFẸ," LAGOS.
P. O. Box 467 Phone 23370.
VOL XIV. No. 817. SATURDAY APRIL 28 - MAY 5, 1962

## Oro Enia Kika Nile Nigeria

A ro si ẹ tọ lati maa fi wosika asaro ọrọ wa ṣe ẹnyin ọkawe wa ni iranti l'ẹkọkan titi ti ẹ̣o ba yio fi ṣe ...... ma ba ṣe ẹnikẹni leri ẹrọ enia kika ti Ijọba wa fẹ ṣe ni ọjọ kẹdogun oṣu May, ti o mbọ yi.

A fẹ ki gbogbo enia mọ wipe ko si ẹrọ owo-ori tabi owo-ode sisan ninu enia kika na rara, ki eyi maṣe jẹ ifoiya fun ẹnikẹni, nitoripe t'ọmọde-t'agba, t'ọkunrin ati obinrin ni nwọn yio ka, lati le mọ iye enia ti o wa ninu awọn ilu kọkan jake jado ilẹ Nigeria.

Anfani nla si ni enia kika na yio ṣe fun awọn enia ile nitoripe nigba mimọ bi enia ti pọ to ni ilu kọkan ni Ijọba yio fi mọ iwọn nkan anfani ti o tọ si ilu bẹ lati ṣe.

Lẹkansi, a tun bẹ ẹnyin enia wa wipe ki ẹ yọnda ara nyin fun awọn oniṣẹ akenia, ki ẹ si ṣe iranlọwọ fun wọn.

### E mase fi omi sofo




## IWE SI OLOTU

### Kinni A Se o?

Ẹ jọwọ, ẹ gba wa, ẹ ba wa bi awọn Ijọba ilu Aganyin (Ghana) lere ẹṣẹ ti a ṣẹ, ti o fi di wipe nwọn ko gb awọn iyawo wa laye mọ lati wọ'lu Ghana wa ba wa.

Laipẹ yi, o to awọn ogun enia ara ilu Nigeria ti awọn ni nwọn ko gbọdọ sọkalẹ si ebute Tarkoradi, ni gbara ti ọkọ ti nwọn wọ ti gunlẹ s'ebute.

Nwọn sọ wipe a ko jẹ ki awọn ọmọ awọn ri iṣẹ ṣẹ mọ; nwọn ni gbogbo iṣẹ kekeke ti awọn ọmọ awọn ko ba maa ṣe ni awọn ara Nigeria ti ra kaka mọ. Bẹ Ijọba Nigeria kii ni ọmọ Ghana kan lara nibikibi niun iṣẹ ni Nigeria.

Ẹ ba wa bere, kini aṣe o?

Emi ni,

Sekondi, Ghana. O. Akande

### Onigbagbo Ko Si Mo, Onigbagbe Lo'Ku

Olotu, e jọwọ ẹ gba mi laye ki nkin nyin lẹhin fun ọrọ wosika ti ẹ fi ki wa ku ọdun lọṣẹ ti o kọja. Ki a maṣe purọ, ọrọ naṣmu awa onigbagb lọkan pupọ.

Ti a ba ni ki a ma ṣe iwasu ẹtitọ ọrọ na, iwe irohin yi a kun patapata. Nitotọ ni ọpọlọpọ awa onigbagbọ ti di onigbagbe, ni ojojumọ ni a nkan Jesu Kristi ti o wa larin wa mọ igi agbelebu pẹlu iwa buruku wa. Iwa awọn ẹlomiran ninu wa si ju ti Judasi lọ.

Ọpọlọpọ awọn onigbagbọ lo ti lọwọ ninu a nfi ọmọ-ọlọmọ wa owo; ẹmiran ni ti on ba ti ndawo kilasi, dandan ni ki on wọ Ijọba ọrun. Iwa ika ati kẹnimani si njọba lọkan wa.

Ẹ ṣọra, Ijọba ọrun ku si dẹdẹ!

Emi ni

Abẹokuta Baba Ijọ



## THE NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED

### ILEYA SHILLING FUND — MAY, 1962

Depositors in the Ileya Shilling Fund are hereby reminded that, in accordance with the Regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Tuesday, 1st May, 1962.

Withdrawals can only be made by the depositor in person and on production of his Passbook. In the case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the branch concerned, such application to be accompanied by the depositor's Passbook for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on the 31st May, 1962, and depositors who fail to withdraw on that day cannot do so until next Ileya.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the depositors' surnames on the date shown here-under and contributors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to until Tuesday, 8th May, 1962.

| | | |
|---|---|---|
| A | — | Tuesday, 1st May |
| B — H | — | Wednesday, 2nd May |
| I — N | — | Thursday, 3rd May |
| O — | — | Friday, 4th May |
| P — Z | — | Saturday, 5th May |
| A & O | — | Monday, 7th May |

For the year 1963, deposits will be taken as from Friday, 1st June, 1962.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER.



## OKUJA WO'LU

NIGBATI OJA KO BA TA, TI ENITI O RA OJA KO TA ENITI O RA, BAWO NI YIO ŞE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIŞOWO LE ŞE TI OJA LE FI MA TA

BI IŞU AKARA GBIGBONA.

# E Polowo Oja Nyin
## Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe

# Em Ka Iwe Irohin Eleti - Ofe
## Ti o kun fun Irohin Aladun Losose


## AWON OLOPA MU WOLI LO SI KOTU GANRAN

ONDO - Gbogbo ęsę awọn ijọ Şọsi aladura kan ti o pe si inu Kotu Adajọ agba laipẹ yi nigbati adajọ kotu na sọ wipe on tun ejo nla ti awọn olopa mba "Woli" kan ti orukọ rẹ nje Şegun Woghiren, eni ọdun mejilelogun, pelu omolẹhin rẹ, Buraimoh Ołokiti, ro siwaju adajọ kotu Ganran (Assizes) ti nwọn nio ṣe ni Iọlọ yi ni Akurẹ.

Ejọ ti awọn olopa ba "Woli" yi ati ọmọ ẹhin rẹ ro nipe awọn mejeji ninu odun to kọja tan obinrin aboyun kan, Funmilayọ Ose, lọ si eti odo kan ninu igbo wipe ki o wa si "abẹ aabo" ki awọn ṣe adura fun un ki o le bi tibi tire.

Awọn olopa ni alo ọkunrin na ni nwọn ri ko si si ẹnikan ti o mọ ibiti aboyun na wa di ẹlo oni.

## Osere Bolu Afesegba



Ogbeni Eusebio da Silva, ti o jẹ ọkan ninu awọn oşere bọlu afẹsẹgba ti ilu Portugal ni a nwo ninu awuran yi ti o fẹ f'ẹsẹ gba bọlu nibiti o ti nşere ni ile itaja kan nilu Oyinbo.

## Jeki Ile-Yin Wa Ni Mimo Nitori Imototo L'ogun Ilera Ati Alafia

Lati ọwọ ONISEGUN "ELETI ỌFẸ"

Lọsẹ to kọja, mo sọrọ nipa Imọtoto fun awọn ọmọ wọ, ṣugbọn lọsẹ yi, ao tẹ siwaju, ao sọrọ nipa imọtoto inu ile wa, iṣẹ mi si ni lati sọ awọn ohun ti o le din aja-alẹ arun ku lode oni, eyi ni pe awọn ti o nti inu idọti is, gegebi ile, onjẹ ati bẹbẹ lọ, ohun ti o le din awọn run yi ku ni imọtoto; nipa pe ki a ma tọju ile wa, ki a ri pe o wa ni mimọ laiko si idọti kan rara.

Eyi ni ọna ti a le ma gba e itọju ile wa, ti yio fi wa ni mimọ, alafia fun enia ninu ile rẹ wa lori onjẹ to dara, ki a si tẹle ofin ilera, eyi ni pe ki awọn ile ati onjẹ wa ma wa ni mimọ, itunu enia ninu ile wa lọwọ bi ile rẹ ti nṣiṣẹ, ati tọju ile ti o ngbe si, ki a ma ra aga, busun ati atupa olowo iyebiye laiko tọju rẹ, bi ẹ ni nfi, owo ṣofo l'o jẹ, bi a ba nra oriṣiriṣi ohun meremere lati fi ṣe ile ni ẹṣọ, ti a ko ba mu oju to tabi ki a ma tọju ile na, asan ni, obinrin ile ni o nmu ile dun, obinrin na ni lati ma ṣiṣẹ rẹ ni ọna ti gbogbo enia yio maa gbadun ile ibiti nwọn ngbe.

Obinrin ile gbọdọ lo gbogbo asiko rẹ lori onjẹ sibẹ, aṣọ fifọ ati ile titọ ju fun awọn ẹbi rẹ, eyi ni awọn ọmọ ati ọkọ rẹ.

### ỌKỌ ATI IYAWO PẸLU ALAFIA

Ọkọ ati awọn ọmọ ni lati mọ pe ile wọn jẹ ibiti wọn ni lati ni alafia ati iranlọwọ nigba gbogbo, ọrọ mi yi jẹ nipa bi a tiṣe ni lati ma tọju ile wa nigba gbogbo, obinrin ile ti o ba nfe alafia fun ọkọ ati awọn ọmọ rẹ, o ni lati ma ka ọrọ mi yi ni ọsṣọsẹ ninu iwe irohin Eleti–Ọfẹ.

## Local Breweries Pleads For Co-operation

In a statement issued by the Nigerian Breweries Limited in Lagos recently the Company sought the co-operation of the trade and the public to stabilise the price of STAR Beer at its new levels effective from 16th April.

The Company pointed out that it had shown its own willingness to assist in achieving this objective by absorbing part of the increased cost resulting from the Budget.

If the financial sacrifice of the Company were to prove effective it could only be by the willing co-operation of the Trade and the Public alike; of the Trade by not charging more than the recommended maximum prices advertised in the national newspapers, and of the Public by insisting on purchasing at the recommended price.

Nigerian Breweries pointed out that the published prices apply to all Nigeria as they operate a free delivery service to selected Nigerian traders in all parts of the country. The Company also hoped that the the trade would appreciate that inflation of prices beyond the recommended maximum could result in a decreased demand for the product to the mutual disadvantage of the Trade and the Company alike.

Furthermore, they hoped that the Trade and the Company could by their mutual co-operation contribute to achieving a balanced cost of living in Nigeria.

## Awon Obinrin Gesi Se Ase Omigbona Fun Omode



Awọn obinrin Gẹsi ti o nṣiṣẹ ninu ọkọ ofurufu ti o nja ogun, ni a nwo ninu aworan yi, nibiti nwọn nfi omi gbigbona (tea) ṣe ase fun awọn ọmọde ilẹ Larubawa (Arab) ninu ọsẹ ti nwọn npe ni "Aden Forces Week". Awọn ọmọde na jẹ igbadun omigbona na pẹlu ere idaraya l'oriṣiriṣi.

## Odun Ipela Ebibi - May, 15th 1962

Ajọdun ọdun Ipẹla ọdunni ni ao ṣe ni Agbara Ẹlẹda ni ọjọ IṢẸGUN ọjọ kẹdogun EBIBI 15th May, 1962, ni "ILE IJUBA" ODUMARE, ni ayika orile ede nla yi pẹlu ilu ati ifọn.

Ọdun ọdun ni papọ mọ ọdun ti Ijọba yio ka iye awọn enia ti nwọn wa ni orile ede nla yi. Ki olukaluku ọdu lati fi otitọ han fun Ijọba, ati ọmọde ati agba, ati ọkunrin ati obinrin ati ọmọ ehin pelu. Ilu Ire olukaluku wa ni orilẹ ede yi ni. Ki iṣe nitori owo ori. Nitorina ki eku ile o wi fun l'oko.

Ẹku Ipamọ ọdun. Ọdun ọdun ni a yabo fun gbogbo wa.

Ọdun aiku, ọdun owo tutu, ọdun Ire gbogbo l ọdun ọdun ni yio jẹ fun gbogbo wa. Aṣẹ.

Gbadebọ Dosunmu
Oludasilẹ ati Olulana
Ijọ Ọrunmila.

## Ijoba Le Awon Omo Ile'we Giga Jade

IBADAN Ni lọlọ yi ni awọn alaṣẹ ile-iwe giga ti a npe ni University College ni Ibadan le ogoje enia ninu awọn akẹkọ ile-iwe giga na jade nitoripe nwọn ko san owo ẹkọ ti nwọn nkọ.

(Wo yoku li ewe kejọ)

## Awon Omo Nigeria Merin Nilu Oyinbo



Awon omo ilẹ Nigeria merin ti nwon je oga onisẹ ero, iṣẹ owo ati agbaṣe iṣẹ nilu Eko, Zaria Ibadan ati Port Harcourt, ti ile iṣe Ajumọsepo ilu Gesi mu lọ silu Oyinbo, ni nwọn lọ pade awon Olugbimọ meji ninu Ile Igbimọ nla nilu Oyinbo laipẹ yi.

Aworan won ni a nwo lati ọtun si osi: Ogbẹni Okronkwo Okereke, Ogbẹni Adebayọ Atanda Alao Ogbẹni Gilbert Babatunde Andre, ati Ogbẹni Oluṣegun Olufade, pẹlu awọn Olugbimọ Ogbẹni George Darling ati Henry Clark.

## Ijoba Le Awo… Omo Ile'we Gig… Jade

(O bere loju ewe keje)

Ogbẹni Slow ti iṣe akapọ… owo ile ẹkọ na ni ọpọlọp… awọn akẹkọ na ni awọn … gba ni imọran wipe k… nwọn yi ẹkọ nwọn pada … eyi ti Ijọba nfẹ enia fu… boya awọn Ijọba le gb… nwọn ṣe iranlọwọ fun'wọn… ṣugbọn awọn ọmọ na … aake kọri.

Baba ẹgbẹ awọn ọmọ ile… ẹkọ na, Ogbeni Abidoye… Babalọla ni on ti sa agbara, on si ti sọ ọrọ awọn ọmọ… ẹgbẹ on ti nwọn le jade na… lodọ Alakoso Ijọba Apapọ… Nigeria, Ọlọla Tafawa… Balewa, ṣugbọn nwọn ko ri… nkankan ṣe si i.

## ALAYE ỌRỌ ẸGBẸ ỌMỌ ILỌRIN

(O bere loju ewe kini)

Ẹ jọwọ, ẹ sọ fun wa, iru iranlọwọ wo ni awọn ẹgbẹ na fẹ ma ṣe fun awọn ọmọ ẹgbẹ na ati fun ara ilu Ilọrin.

Ọrọ mi ko ju eyi lọ.

Emi ni,
Y. Amoda
Ọmọ Ilọrin.


## LAGOS RACE CLUB

### EASTER MEETING, 1962.

Saturday 21st, Monday 23rd, Saturday 28th April, 5th & 12th May 1962.

Racing Starts at 2.45 p.m. each day of the Meeting.

DECLARATION

Declaration will be made at the Secretary's office between the hours of 1.30 p.m. and 1.45 p.m. on Racing Days.

ADMISSION TICKETS (ADVANCE PURCHASE)

ADMISSION TICKETS for the Meeting can be purchased in advance at the Secretary's Office in the Paddock between the hours of 5 and 6 p.m. on the day preceding each day of the Meeting.

Admission : 3/- per day
including Entertainment Tax

CHILDREN

No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.


## Eleti—Ofe D'araba

# Awujale Losi Mekka

Awujalẹ ti ilẹ Ijẹbu, Alaiyeluwa Ọba Sikiru Adetọna, jẹ ọkan ninu awọn arinrin-ajo mejileladọta-lerugba enia ti o lọ si ilẹ mimọ Mẹka lati ipinlẹ Iwọ-orun, Nigeria ni ọdun yi.

Tẹlẹtẹlẹ, awọn Igbimọ eleto awọn ero Mẹka ti ṣe eto ọkọ ofurufu silẹ fun ọjọ mẹta, ọjọ 26, 27 ati 28 oṣu April yi lati ko wọn lọ.

Awujalẹ ti yio ba ọkọ ti ọjọ 28, lọ ni aburo rẹ okunrin Ogbẹni R. A. Adetọna ati awọn Oloye rẹ meji, Oloye L. A. Akinsanya, Olisa Ijẹbu-ode ati Oloye I. W. Oshilaja mba lọ. Lẹhinti Ọba na ba ti ṣe Hadji tan, yio rekọja si ilu Cairo, Jerusalẹm, Beirut ati ilu nla London ki o to pada wa sile.

Adura ti awa "Eleti-Ọfẹ" ni ki Oluwa Olodumare ba wa ṣọ Ọba yi, ki o le ṣe iṣẹ na ni aṣepe, ki o si pada wa si ile pẹlu alafia.

Asalatu l-Nọbiyi Karim.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23376; Ọtọlu L. A. OJO, 12 Inabere Street, Lagos.